**9.** Nitorina ki o mã şe işinileti, nigbati isinileti naa ba wulo.

فَذَكِّرْ إِن نَّفَعَتِ ٱلذِّكْرَىٰ ٩

**10.** Ẹniti o npaiya (Ọlọhun) yio ma tẹti si i.

سَيَذَّكَّرُ مَن يَخْشَىٰ ١٠

**11.** Bẹ si ni oloriburuku yio ma takete si i.

وَيَتَجَنَّبُهَا ٱلْأَشْقَى ١١

**12.** Ẹniti yio wọ ina ti o tobi.

ٱلَّذِى يَصْلَى ٱلنَّارَ ٱلْكُبْرَىٰ ١٢

**13.** Lẹhinna kò ni ku ninu rẹ bẹ si ni kò ni jẹ abẹmi.

ثُمَّ لَا يَمُوتُ فِيهَا وَلَا يَحْيَىٰ ١٣

**14.** Dajudaju ẹniti o ba şe mimọ ti jere.

قَدْ أَفْلَحَ مَن تَزَكَّىٰ ١٤

**15.** Ti o si nranti orukọ Oluwa (Ọba) rẹ ti o si nkirun.

وَذَكَرَ ٱسْمَ رَبِّهِۦ فَصَلَّىٰ ١٥

**16.** Şugbọn aiye ni ẹ wà maiya.

بَلْ تُؤْثِرُونَ ٱلْحَيَوٰةَ ٱلدُّنْيَا ١٦

**17.** Bẹ si ni ọrun lo dara julọ ti yio si ma bẹ titi (şẹ kù).

وَٱلْـَٔاخِرَةُ خَيْرٌ وَأَبْقَىٰٓ ١٧

**18.** Dajudaju eyi mbẹ ninu awọn tirà ti akọkọ.

إِنَّ هَـٰذَا لَفِى ٱلصُّحُفِ ٱلْأُولَىٰ ١٨

**19.** Tirà Ibrahima ati ti Musa.

صُحُفِ إِبْرَٰهِيمَ وَمُوسَىٰ ١٩

## *(88) Suratul - Gãşiyah*

## سُورَةُ ٱلْغَاشِيَةِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَـٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Njẹ ọ̀rọ nipa ohun ti yio ma bo enia mọlẹ daru ‘Gãşiyah’ ti wa ba ọ?

هَلْ أَتَىٰكَ حَدِيثُ ٱلْغَـٰشِيَةِ ١

**2.** Awọn oju kan yio dorikodo niti yẹpẹrẹ ni ọjọ na.

وُجُوهٌ يَوْمَئِذٍ خَـٰشِعَةٌ ٢

**3.** Yio şe wahala pupọ yio si rẹ̀ ẹ.

عَامِلَةٌ نَّاصِبَةٌ ﴿٣﴾

**4.** Nwọn yio jo ina kan ti o gbona.

تَصْلَىٰ نَارًا حَامِيَةً ﴿٤﴾

**5.** A o fun u ni omi gbigbona mu.

تُسْقَىٰ مِنْ عَيْنٍ ءَانِيَةٍ ﴿٥﴾

**6.** Kòsi onjẹ kan fun wọn ayafi ẹ̀gũn.

لَّيْسَ لَهُمْ طَعَامٌ إِلَّا مِن ضَرِيعٍ ﴿٦﴾

**7.** Kò ni mu wọn sanra bẹ si ni kò ni yo wọn.

لَّا يُسْمِنُ وَلَا يُغْنِي مِن جُوعٍ ﴿٧﴾

**8.** Awọn oju miran yio ma tutu daradara ni ọjọ na.

وُجُوهٌ يَوْمَئِذٍ نَّاعِمَةٌ ﴿٨﴾

**9.** Yio yọnu si ẹsan işẹ rẹ̀ (ti o şe).

لِّسَعْيِهَا رَاضِيَةٌ ﴿٩﴾

**10.** Ninu ọgba idẹra ti o ga.

فِي جَنَّةٍ عَالِيَةٍ ﴿١٠﴾

**11.** Nwọn ko ni gbọrọ isọkusọ ninu rẹ̀.

لَّا تَسْمَعُ فِيهَا لَٰغِيَةً ﴿١١﴾

**12.** Isẹlẹru omi ti o nsàn mbẹ ninu rẹ̀.

فِيهَا عَيْنٌ جَارِيَةٌ ﴿١٢﴾

**13.** Awọn ibusun ti o ga mbẹ ninu rẹ̀.

فِيهَا سُرُرٌ مَّرْفُوعَةٌ ﴿١٣﴾

**14.** Ati awọn ife ti a ti fi lelẹ̀.

وَأَكْوَابٌ مَّوْضُوعَةٌ ﴿١٤﴾

**15.** Ati awọn irọri ti a tò gbe ara wọn.

وَنَمَارِقُ مَصْفُوفَةٌ ﴿١٥﴾

**16.** Ati awọn itẹ ti a ti tẹ silẹ̀.

وَزَرَابِيُّ مَبْثُوثَةٌ ﴿١٦﴾

**17.** Ẽşe ti awọn kò wo rakunmi bi a ti şe da a?

أَفَلَا يَنظُرُونَ إِلَى ٱلْإِبِلِ كَيْفَ خُلِقَتْ ﴿١٧﴾

**18.** ki nwọn si wo sanma bi a ti gbe e ga.

وَإِلَى ٱلسَّمَآءِ كَيۡفَ رُفِعَتۡ ١٨

**19.** Ki nwọn si wo awọn òke bi a ti şe kan (a) mọlẹ̀.

وَإِلَى ٱلۡجِبَالِ كَيۡفَ نُصِبَتۡ ١٩

**20.** Ki nwọn si wo ilẹ̀ bi a ti şe tẹ ẹ nitẹ.

وَإِلَى ٱلۡأَرۡضِ كَيۡفَ سُطِحَتۡ ٢٠

**21.** Nitorina mã şe iranti. Dajudaju irẹ jẹ oluşe iranti nikan ni.

فَذَكِّرۡ إِنَّمَآ أَنتَ مُذَكِّرٞ ٢١

**22.** O kò jẹ olujẹni-nipa fun wọn.

لَّسۡتَ عَلَيۡهِم بِمُصَيۡطِرٍ ٢٢

**23.** şugbọn ẹniti o ba pẹhinda ti o şe aigbagbọ.

إِلَّا مَن تَوَلَّىٰ وَكَفَرَ ٢٣

**24.** Nitorina Ọlọhun yio jẹ ẹ niyà ti o tobi.

فَيُعَذِّبُهُ ٱللَّهُ ٱلۡعَذَابَ ٱلۡأَكۡبَرَ ٢٤

**25.** Dajudaju àbọ̀ wọn ọdọ Wa ni.

إِنَّ إِلَيۡنَآ إِيَابَهُمۡ ٢٥

**26.** Lẹhinna Awa ni A o şiro işẹ wọn.

ثُمَّ إِنَّ عَلَيۡنَا حِسَابَهُم ٢٦

## *(89) Suratul - Fajri*

## سُورَةُ الفَجۡرِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aşakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi afẹmọjumọ (Al-Fajri) bura.

وَٱلۡفَجۡرِ ١

**2.** Ati oru mẹwa kan.

وَلَيَالٍ عَشۡرٖ ٢

**3.** Ati nkan oni mejimeji ati nkan ẹyọ kanşoşo (bura).

وَٱلشَّفۡعِ وَٱلۡوَتۡرِ ٣